# AṢẸ́GUN

**Jobu 17:9; Luku 9:62; 1 Johannu 5:4**

**Ifihan 2:7, 11, 17, 26, 27; 3:5, 12, 21**

**ẸKỌ 425 --- FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: "Ẹniti o ba ṣẹgun ni yio jogún nkan wọnyi; emi o si mã jẹ Ọlọrun rẹ, on o si mã jẹ ọmọ mi" (Ifihan 21:7).**

**Ririn Ninu Imọlẹ**

Ẹkọ wa ti oni jẹ lori aṣẹ́gun. Aṣẹ́gun ni ẹni ti ko da ẹ̀ṣẹ, ẹni ti o gbọran si gbogbo aṣẹ Ọlorun ti o gbọ nipa rẹ. Pe a ti tun wa bí ati pe a ti di Onigbagbọ́, ko to rara. A gbọdọ maa rin ninu imọlẹ ti Ọlorun fi fun wa. Nigba ti Ọlọrun ba fi hàn wa ninu Bibeli Rẹ̀ ohun miiran ti o ta eyi ti a ti gba yọ, a gbọdọ wa ohun naa ki a si gba a pẹlu. Ọlọrun ni ọpọlọpọ ibukun iyanu fun awọn eniyan Rẹ̀, O si ni inudidun lati maa fi awọn ibukun wọnyii fun wọn. Ṣugbọn a gbọdọ gbọran si gbogbo ofin Rẹ̀, a si gbọdọ gba pe ki O ṣamọna igbesi-ayé wa, bi a ba fẹ ki awọn ibukun wọnyii jẹ́ ti wa.

"Ipa-ọ̀na awọn olõtọ dabi titàn imọlẹ, ti o ntàn siwaju ati siwaju titi di ọsangangan" (Owe 4:18). Bi ọjọ ti n gori ọjọ ti a si n rin ninu imọlẹ, bẹẹ ni a o maa jọ Jesu si i siwaju ati siwaju. Ko yẹ fun wa rara lati tun pada lati maa dẹṣẹ. Ọlọrun ni agbara lati pa wa mọ bi a ba fẹ bẹẹ. "Nitori olukuluku ẹniti a bi nipa ti Ọlọrun o ṣẹgun aiye" (1 Johannu 5:4).

Ṣugbọn bi eniyan bá dá ẹ̀ṣẹ tabi ti o ba kuna lati rin ninu imọlẹ ti Ọlọrun fi fun un, imọlẹ naa yoo di okunkun, oun ki yoo si jẹ aṣẹgun. Bibeli kọ́ wa pe a gbọdọ sọ wa di mimọ́ lẹyin ti a ba ti ri igbala. Bi imọlẹ yii ba mọlẹ si wa ti a si kọ̀ lati rin ninu rẹ̀, a o sọ igbala wa nù. Oluwa n sọ ohun ti a gbọdọ ṣe fun wa, ṣugbọn bi a ba kọ̀ lati ṣe e, a ki yoo le jẹ́ aṣẹgun.

"Kò si ẹni, ti o fi ọwọ́ rẹ̀ le ohunelo itulẹ, ti o si wò ẹhin, ti o yẹ fun ijọba Ọlọrun" (Luku 9:62). Bi eniyan ba wo ẹyin nigba ti o ba n kọ ebe lọ, aporo rẹ yoo bẹrẹ si i wọ́. O gbọdọ kọju si ọkankan ibi ti o n lọ gan an ki aporo rẹ̀ ba le gún. Bẹẹ gẹgẹ ni Onigbagbọ gbọdọ tẹ oju rẹ̀ mọ opin ire-ije rẹ̀, iye ainipẹkun, bi bẹẹ kọ́ ipa-ọna rẹ̀ yoo di wiwọ́. Ohun ti o jẹ olori ero rẹ ni lati wu Ọlọrun. Boya nigba kan a ti gba a là o si ti n sin Ọlọrun ni otitọ, ṣugbọn o tun bẹrẹ si i wo awọn ohun igbadun ti o lù mọ ẹ̀ṣẹ tabi o ti pada di ẹni ti o ni ifẹ si jijere awọn ohun ayé yii ju lati maa jọ Jesu siwaju si i, nitori naa o sọ ifẹ tootọ lati wu Ọlọrun naa nù.

**Awọn Ero Wa**

Bibeli wi pe: "Mã sá fun ifẹkufẹ ewe: si mã lepa ododo, igbagbọ́, ifẹ, alafia, pẹlu awọn ti nkepè Oluwa lati inu ọkàn funfun wá" (2 Timoteu 2:22). Ero nipa awọn ohun ti o lù mọ́ ẹ̀ṣẹ eyi ti awọn ẹlomiran n ṣe le maa fa awọn ọdọmọde lati ṣe aibikita nipa iwa hihu ti wọn to bẹẹ ti wọn o fi padanu anfaani wiwà ni mimọ́ ọkàn wọn. Kiki rironu lori awọn ohun ti o lù mọ́ ẹ̀ṣẹ eyi ti awọn ẹlomiran n ṣe paapaa le sọ ọkàn di eleeri. A sọ fun wa ninu Ọrọ Ọlọrun ohun ti o yẹ ki a maa ronu nipa rẹ̀: "Ohunkohun ti iṣe ọ̀wọ, ohunkohun ti iṣe titọ́, ohunkohun ti iṣe mimọ́, ohunkohun ti iṣe fifẹ, ohunkohun ti o ni irohin rere; bi ìwa titọ́ kan ba wà, bi iyin kan ba si wà, ẹ mã gbà nkan wọnyi rò" (Filippi 4:8).

**Riri Jesu Nipa Igbagbọ́**

Nigba ti a ba tun wa bi, Jesu a di ẹni ti a ni imọ Rẹ̀, bi ẹni pe o wa lọdọ wa ninu ara. Nipa igbagbọ ni a fi "ri I." A ni idaniloju pe O wà pẹlu wa to bẹẹ ti a fi le ke pe E nigbakigba ti a ba wà ninu aini. O jẹ́ ọrẹ ti O sun mọ wa timọ-timọ nigba gbogbo. A sọ fun wa nipa ti Mose pe: "Nipa igbagbọ́ li o kọ̀ Egipti silẹ, li aibẹ̀ru ibinu ọba: nitoriti o duro ṣinṣin bi ẹniti o nri ẹni airi" (Heberu 11:27). O duro ṣinṣin; o jẹ́ aṣẹ́gun. Oun kò fi oju ri Jesu ṣugbọn o mọ pe O wà pẹlu oun.

Wo bi i ba ti jẹ́ ohun iyanu tó lati bá Jesu rin nigba ti O wà ninu ayé! Ṣugbọn ọpọ eniyan ni o ri I sibẹ ti wọn ko gba A gbọ́. Fun ọkan ninu awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀, Jesu wi pe: "Nitoriti iwọ ri mi ni iwọ ṣe gbagbọ́: alabukun-fun li awọn ti kò ri, ti nwọn si gbagbọ́" (Johannu 20:29). Awa wà ninu awọn wọnni ti o gba Jesu gbọ́ bi o tilẹ jẹ pe a kò fi oju ri I ninu ara rí. Jesu ni gbongbo igbagbọ́ wa. "Eyi si ni iṣẹgun ti

o ṣẹgun aiye, ani igbagbọ́ wa" (1 Johannu 5:4). Bi a ti n fi ayé wa rubọ si Ọlọrun to bakan naa ni a n pa igbagbọ́ wa mọ́ ninu Rẹ̀. Nigba naa ni a le jẹ igbadun awọn ibukun Rẹ̀, a o si jẹ́ aṣẹ́gun.

Jesu wi pe bi a ba gba Oun gbọ a o pa aṣẹ Oun mọ́. Awọn aṣẹ Ọlọrun a maa mu inu wa dùn: wọn jẹ́ imọlẹ si ipa ọ̀na wa, wọn jẹ́ ikunra fun awọn ipọnju wa, wọn jẹ́ ounjẹ fun ọkàn wa. Wọn n kọ́ wa nipa ododo, wọn si n ba wa wi nigba ti a ba ṣe aṣiṣe. Wọn maa n ki wa laya nigba ti a ba wa ninu wahala, wọn n mu wa dagba, wọn si n fi ẹsẹ wa mulẹ ninu igbagbọ.

**Ṣiṣe Ẹkọ ni Ọṣọ**

A kọ wa pe ki a "mã ṣe ẹkọ́ Ọlọrun Olugbala wa li ọṣọ́ ninu ohun gbogbo" (Titu 2:10). Paulu wi fun awọn ara Kọrinti pe, "Ẹnyin ni iwe wa, ti a ti kọ si wa li ọkàn, ti gbogbo enia ti mọ̀, ti nwọn si ti kà" (2 Kọrinti 3:2). Aṣẹ́gun a maa tàn bi imọlẹ laaarin awọn ẹlẹṣẹ, a si maa fi iyatọ ti o hàn gbangba ti o wà laaarin Onigbagbọ ati ẹlẹṣẹ hàn fun ayé. Igbesi-aye rẹ̀ a "mã ṣe ọṣọ́" fun ijọ, a si fi kun ẹwà Ẹsin-Igbagbọ́.

Igbesi-ayé ti a n gbé ninu ayé yii n tọka si ayeraye. Nigba ti a ba ni Kristi ninu wa, yoo rọ̀ wa lọrun lati gbé igbesi-ayé Onigbagbọ́. Awa kò le jẹ́ aṣẹgun nipa ipá ti awa tikara wa, ṣugbọn nigba ti a ba mu ipá ti Ọlọrun lò, nigba naa ni a le jẹ́ aṣẹ́gun. Ninu Oniwasu 9:11 a kà pe: "Mo pada, mo si ri labẹ õrùn, pe ire-ije kì iṣe ti ẹniti o yara, bẹ̃li ogun ki iṣe ti alagbara." Kì i ṣe pe awọn ti o jẹ alagbara nipa ti ẹda ni yoo ni agbara jù ninu iṣẹ Oluwa. Nipa Ẹmi Ọlorun ni a fi n di "akọni" fun Un. "Kì iṣe nipa ipá, kì iṣe nipa agbara, bikoṣe nipa Ẹmi mi, ni OLUWA awọn ọmọ-ogun wi" (Sekariah 4:6).

**Ire-ije ti Onigbagbọ́**

Paulu Apọsteli fi igbesi-ayé Onigbagbọ́ wé ire-ije. O ni ninu ire-ije ti ayé ti a n sá ẹni kan ṣoṣo ni o n gba ère, ṣugbọn ninu ire-ije ti Ọlọrun gbogbo wa le sare ni ọna ti a o fi gba èrè. O wi pe: "Nitorina bi a ti fi awọsanma ti o kún to bayi fun awọn ẹlẹri yí wa ká, ẹ jẹ ki a pa ohun idiwọ gbogbo tì si apakan, ati ẹ̀ṣẹ ti o rọrun lati dì mọ wa, ki a si mã fi sũru sure ije ti a gbé ka iwaju wa" (Heberu 12:1). Nigba miiran ire-ije wa le fà diẹ nitori iyiiriwo, aisan, ati awọn nnkan miiran, ṣugbọn a ṣi n sare sibẹ. "Ẹni ti o rọra n sare bi-o-ti-o-ti-wu-ki-o-ri, yoo de opin" Ọlọrun ni èrè nla ti O ti pese silẹ fun awọn wọnni ti yoo sare ije naa dé opin, pẹlu suuru.

**Ogun**

Paulu tún fi igbesi-ayé Onigbagbọ́ wé ogun jijà. Ọlọrun n fẹ ọmọ-ogun ti yoo "gba a mu ni irungbọ̀n," ọmọ-ogun ti kì yoo sá kuro loju ija nigba ti ogun naa ba le. Ọmọ-ogun ti ifẹ ti rẹ̀ kì i ṣe ninu tito lọwọọwọ lati fi aṣọ awọn ọmọ-ogun hàn nikan. Bi ijẹwọ igbagbọ́ eniyan ti mọ maa n di mimọ̀ nipa igbagbọ́ ti eniyan fi hàn ni akoko ti o dojukọ iṣoro ti o le jù lọ. Ẹnikẹni le gbé igbesi-ayé rere nigba ti ohun gbogbo ba n lọ deedee fun un; nigba ti a ba dán an wo nikan ṣoṣo ni a le mọ ohun ti o wa ninu ọkàn rẹ̀ gan an. Ọlọrun ti ṣeleri pe ninu gbogbo idanwo Oun yoo ṣe ọna atiyọ bọ́ ninu rẹ̀. Ẹni ti o ba ṣojo ninu iṣoro kò mu ibukun bá ẹnikẹni. Oun ki i ṣe iranwọ fun awon ero ti o wà loju ọna, bi ko ba si ronupiwada oun yoo sọ ẹmi ara rẹ̀ nù.

Nigba ti idanwo lile ba dé, wolẹ niwaju Ọlọrun ki o si pinnu ninu ọkàn rẹ pe o to akoko gan an lati jà fun Oluwa. Nisisiyii ni akoko lati jẹ́ ọmọ-ogun rere. Nigba ti iwọ ba gbadura, iwọ yoo lé ọpọlọpọ ẹgbẹ ọmọ-ogun eṣu sá. Ọlọrun ti ṣeleri pe, "Ọkunrin kan ninu nyin yio lé ẹgbẹrun: nitoripe OLUWA Ọlọrun nyin, on li ẹniti njà fun nyin, gẹgẹ bi o ti sọ fun nyin" (Joṣua 23:10). Ọlọrun n jà fun awọn wọnni ti wọn gbọran si i lẹnu ati ti wọn fi gbogbo ọkàn wọn gbẹkẹle E. O ṣeleri pe: "Kiyesi i, emi fun nyin li aṣẹ … lori gbogbo agbara ọtá" (Luku 10:19). O fi aṣẹ yii fun wa ninu ayé yii, nitori nigba ti ayé wa ba pari nihin a o bọ́ ihamọra wa silẹ. Awa yoo si ṣẹ́gun. Ade ododo ani iye ainipẹkun ni yoo jẹ́ ere aṣẹ́gun.

**Awọn Ileri fun Aṣẹ́gun**

Ọlọrun ti ṣe ileri ohun iyanu pupọ fun aṣẹ́gun. "Ẹniti o ba ṣẹgun ni emi o fi eso igi ìye nì fun jẹ, ti mbẹ larin Paradise Ọlọrun" (Ifihan 2:7). A o wa laaye laelae. Nigba ti eniyan dẹṣẹ ninu Ọgba Edẹni, Ọlọrun fi awọn kerubu yi Igi Ìye ká lati má ba jẹ ki awọn ẹlẹṣẹ ni anfaani lati jẹ ninu rẹ̀ ki wọn si yè titi. Njẹ ki yoo ha jẹ ohun ti yoo buru bi awọn eniyan buburu ba le wà ninu ayé titi lae lati maa hu iwa

buburu wọn? Ṣugbọn nigba ti aṣẹgun ba dé Ọrun, Ọlọrun yoo fun un ni anfaani lati jẹ lara igi nì, yoo si wà laaye titi lae.

"Ẹniti o ba ṣẹgun kì yio farapa ninu ikú keji" (Ifihan 2:11). Ikú keji jẹ idalẹbi ayeraye. Aṣẹgun ko ni tun bẹru pe oun yoo sọ igbala oun nù ati pe oun yoo lọ si ọrun-apaadi. Lẹẹkan ti o ba ti wà laaye ni Ọrun, o wà laaye titi lae ni.

"Ẹniti o ba ṣẹgun li emi o fi mana ti o pamọ́ fun jẹ, emi o si fun u li okuta funfun kan, ati sara okuta naa orukọ titun ti a kọ si i, ti ẹnikẹni kò mọ̀ bikoṣe ẹniti o gbà a" (Ifihan 2:17). Awọn ohun aṣiiri iyebiye wà laaarin awa ati Ọlọrun bi a ba jẹ́ aṣẹ́gun. A le ba A sọ awọn ohun wọnni ti a ko le bá ẹlomiran sọ rara, wọn yoo si ye E, Oun yoo si boju to wọn. Oun yoo fun wa ni orukọ eyi ti ẹnikẹni ko le mọ̀, ṣugbọn nigba ti O ba fi orukọ yii pe wa a o mọ ọn.

"Ẹniti o ba si ṣẹgun, ati ẹniti o ba pa iṣẹ mi mọ́ titi de opin, emi o fun u li aṣẹ lori awọn orilẹ-ède: on o si mã fi ọpá irin ṣe akoso wọn" (Ifihan 2:26, 27). A gbọdọ ṣe oloootọ titi de opin ki a ba le gba ère ti Ọlọrun ni fun wa. Bi awa ba bá Kristi jiya nihin, a o si ba A jọba pẹlu. A o ni aṣẹ lati ṣe akoso awọn orilẹ-ède pẹlu ọwọ lile - pẹlu ọpá irin. Gbogbo eniyan ni yoo gbọran si awọn ofin ti Jesu yoo fi lelẹ ninu ijọba Rẹ lori ilẹ ayé.

"Ẹniti o ba ṣẹgun, on na li a o fi aṣọ funfun wọ̀; emi kì yio pa orukọ rẹ rẹ́ kuro ninu iwe ìye, ṣugbọn emi o jẹwọ orukọ rẹ niwaju Baba mi, ati niwaju awọn angẹli rẹ" (Ifihan 3:5). Jesu yoo fi ọlá fun awọn aṣẹgun, awọn ti wọn ti gbọran si Ọrọ Rẹ, awọn ti o ti sin I lotitọ ninu ayé yii laaarin inunibini. Oun yoo jẹwọ awọn oloootọ wọnni niwaju Baba, gbogbo awọn angẹli yoo maa wo, wọn yoo si maa yọ ayọ̀ pe Ẹjẹ Jesu ra wọn pada, o sọ aṣọ wọn di funfun, o si ṣe wọn yẹ lati wà ni Ọrun pẹlu Jesu ati awọn angẹli Rẹ. Nigba ti a tun wọn bi, a kọwe orukọ wọn ni Ọrun, wọn kò si dá ẹṣẹkẹṣẹ ti o le mu ki a pa orukọ wọn rẹ́.

"Ẹniti o ba ṣẹgun, on li emi o fi ṣe ọwọ̀n ninu tẹmpili Ọlọrun mi, on kì yio si jade kuro nibẹ mọ́: emi o si kọ orukọ Ọlọrun mi si i lara, ati orukọ ilu Ọlọrun mi, ti iṣe Jerusalẹmu titun, ti o nti ọrun sọkalẹ lati ọdọ Ọlọrun mi wá: ati orukọ titun ti emi tikarami" (Ifihan 3:12). Lọjọ oni, Jesu ni Olori Alufaa wa, ṣugbọn nigba ti O ba tun pada wa Oun yoo jẹ́ Ọba awọn ọba ati Oluwa awọn oluwa, awọn eniyan Rẹ yoo si jọba pẹlu Rẹ. Oun yoo kọ orukọ Rẹ si wọn lara, yoo si fi ami Rẹ sara wọn, ti gbogbo eniyan yoo fi mọ̀ pe awọn wọnyii ni ẹni irapada, awọn wọnni ti O kú fun.

Awọn eniyan Rẹ jẹ ọwọ̀n, Ọwọ̀n jẹ ohun ti o ṣe e sinmi lé. Ki i sọrọ rara, ki i kuro nibi ti a ba mọ ọn si, oun ni i maa gbé orule soke o si ṣe pataki pupọ. Ọmọ Ọlọrun le ṣe oloootọ ninu ile Ọlọrun pẹlu gẹgẹ bi ọwọ̀n ti ṣe e sinmi le.

Ni opin gbogbo rẹ O wi pe: "Ẹniti o ba ṣẹgun li emi o fifun lati joko pẹlu mi lori itẹ́ mi, bi emi pẹlu ti ṣẹgun, ti mo si joko pẹlu Baba mi lori itẹ́ rẹ" (Ifihan 3:21). Nigba ti Jesu wà ni ayé, O ti fara da ohun gbogbo ti awa yoo fara dà, lati fi hàn pe o ṣe e ṣe fun wa lati ṣẹgun. Nitori O ti ṣẹgun, awa paapaa le ṣẹgun, bi a ba fi ipá Rẹ ṣe agbára wa. Nigba ti gbogbo ogun ba pari, ti gbogbo iṣẹ si pari, a le joko pọ̀ pẹlu Jesu lori Itẹ́ Rẹ.

## AWỌN IBEERE

1 Ki ni le sọ imọlẹ Ihinrere di okunkun fun wa?

2 Ki ni ẹni ti n fi ajaga maluu tulẹ ni lati ṣe ki aporo rẹ to le run?

3 Ki ni Bibeli sọ pe ki a maa ronu nipa rẹ?

4 Bawo ni a ṣe le "ri" Jesu nisisiyii?

5 Ọna wo ni Onigbagbọ́ le gba ṣe ẹ̀kọ́ lọṣọ?

6 Ọna wo ni Paulu gba fi igbesi-ayé Onigbagbọ́ wé ire-ije? Fi wé ogun jija?

7 Darukọ diẹ ninu awọn ileri ti Ọlọrun ṣe fun aṣẹgun.